# ÌLÚ NEW YORK NÍ LÁTI KÀ Ọ́!

## Kínni ìkànìyàn náá?

Ìkànìyàn náá ka gbogbo ènìyàn tí on gbe ní òrílẹ̀ èdè United States.

Ó maa n waye ní gbogbo ọdún mẹwà-mẹwà.

## Ìkànìyàn náá ó tọkàsí:

- Ọgọọgọ̀rún ọkẹ́ àimọye owó ìjọba àpapọ̀ fún ẹ̀kọ́ gbogboogbò, ètò ìlera, ilé òlowopọ́ọ́kú, ohun àmáyédẹrùn àti bẹẹ lọ.
- Iye àyè New York ní ìgbìmọ̀.
- Bí a ṣé n ṣe àwọn ìpinu tí ó ṣe kókó nípa ètò àbẹle, ètò pàjáwìrì, ìrinnà, ìlera, àti bẹẹ lọ, èyí tó dá lórí data tó ṣe déédé.

### ÌKÀNÌYÀN NÁÁ NÍ IPA LÓRI ÌPÍN ỌGBA OGỌỌGỌ̀RÚN ỌKỆ ÀIMỌYE FÚN:

- Ètò ìṣèdúró ìlera àwọn ogówẹ́ẹ́rẹ́ (Children's Health Insurance Program, CHIP), ẹ̀kọ́, awọ́n olùkọ́, ìpèsè, àti àwọn ètò ẹ̀yìn ẹ̀kọ́ pẹ̀lú fún àwọn ọmọ àkàndá àti àwọn tán wá láti ebí kòlàkòṣagbe.
- Ẹ̀kọ́ àgbà, ètò ìdánilẹ́kọ nípa iṣẹ́, pẹ̀lú ètò ìjẹnilógún fún àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀, àjòjì-bí, àkàndá àti àwọn olùṣẹ̀jọ́ tí wọ́n jẹ́ olùgbé ìlú New York.
- Àwọn ìgbéga íbùdó àgbà ati ètò, pẹ̀lú oúnjẹ.
- Ìrànlọ́wọ́ lórí iléégbé tí kò gunpá (Abala 8), àmójútó, àtùnṣe, àti àwọn ìtẹ̀síwájú.

## Nítòrínaa la ṣe nílò gbogbo ará ìlú New York láti jẹ́ kíkà.

Tí o bá kópa níbi ìkànìyàn náá, o tún ọjọ́ọ̀la àwọn àwùjọ wa ṣe ní.

Ní ọdún 2010, **62%** péré ará ìlu New York ni wọ́n fúnrawọn kópa nínu ìkànìyàn naa léyi tó kéré sí **76%** gbogbo ìlú.

**Tí púpọ̀ àwọn èyàn ìlú New York bá kópa ni ọdún 2020, a maa rí owó tó pọ̀ fún àwọn ilé-ẹ̀kọ́ wa, fún èto ìlera àti fún àwọn ètò tí a gbẹkẹ̀lé lójoojúmọ́.**

# Kínni ìkanìyàn náá bèrè?



- Ènìyàn melò lón gbé tàbí ló wà ní ilé rẹ?
- Ọ́kunrín niwọ́n tàbí óbinrín, kínni ọjọ́ orí wọn àti ẹ̀yà wọn
- Yálà ilé-ìgbé rẹ jẹ́ tiẹ tàbí èyí tí o yá gbé.
- Àdírẹ́sì ilé rẹ

**Ìkànìyàn ọdún 2020 kò bèèrè nípa:**

- *Ipò ìwọlé àti ìjáde tàbí ìgbélu*
- *Èèrè*
- *Númbà ààbò àwùjọ*

# Ìròyìn nípa rẹ yóó wà ní ìpamọ́!






- Gbogbo èsì ló pamọ́, tí ó ní ìdáábòbò lábẹ́ òfin tí kò sì le jẹ́ àtakò fún ọ ní ọ̀nàkọ̀nà.
- Lábẹ́ òfin, àjọ ìkànìyàn kò lẹ́tọ láti fi ohunkóhun nípa rẹ sílẹ̀ fún àjọ ìjọba míràn, pẹ̀lú àjọ agbófinró.

**Ìjìyà ìtàpásófin yíí tó ẹ̀wọ̀n ọdún márun àti owó ìtánràn tí iye rẹ̀ jẹ́ $250,000.**

# Báwoni ìlú New York ṣé n gbáradì fún ìkànìyàn náá?

Ní ọdún 2019, ìgbìmọ̀ ìsàkóso de Blasio ṣe ìfilọ́ọ́lẹ̀ ìkànìyàn NYC ti 2020, àkọ́kọ́ irú rẹ̀ lójúnà àti ṣe àrídájú kíka àwọn ènìyàn ìlú New York ní pípé àti déédé fún ti ìkànìyàn ọdún 2020. Ètò náá ṣe àkójọpọ̀:

- Àjọ ìsàkójọpọ̀ owó fún ìkànìyàn tí ó pé ní ìlú New York pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ìsàkóso de Blasio àti ìgbìmọ̀ ìkówójọ ìlú fi $19million sóri ẹ̀kọ́ ìkànìyàn àti ètò kóríyá gbati àwọn àjọ àwùjọ tí àwọn ènìyàn ìlú New York mọ̀ tí wọ́n sì le gbẹ́kẹ̀lé.
- Ìsisẹ́pọ̀ àwọn àjọ tí ó rísí agbára 350,000 òsìsẹ́ ìlú àti àwọn ilé-iṣẹ́ pàtàkì ní ìlú, pẹ̀lú yàrá ìkàwé, ilé-ìwòsàn àti ilé ìjọsìn, àṣà àti àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga.
- Ìpolongo orí pápá àti ìtajà tí ìlú darí dé ọ̀dọ̀ gbogbo ènìyàn ìlú New York. Fa ararẹ kalẹ̀ ní agbègbè rẹ: **nyc.gov/census**

# Ìgbà wo ni ìkànìyàn náá ó bẹ̀ẹ̀rẹ̀?

**12 Ẹ̀RẸ̀NÀ, ỌDÚN 2020** **my2020census.gov**




Fún ìgbà àkọ́kọ́, wà á ní ànfàní láti kópa níbi ìkànìyàn náá lorí ẹ̀rọ ayélujára, gbati méélì tàbí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti ède onírùurú.

Ẹ wo akoto méélì yín fún ìròyìn láti ọ̀dọ̀ àjọ ìkànìyàn nípa bí ẹṣelè fíìli fọ́ọ̀mù.

Gbogbo ibùdó ìkàwé tí ó jẹ́ ti NYC àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àjọ àdúgbò tí wọ́n ṣé gbẹ́kẹ̀lé ni wọn maa pèse ìrànlọ́wọ́ láti fíìli fọ́ọ̀mù.

Fún àfikún ìmọ̀, ẹ lọ:
**nyc.gov/census**

yo_08